# ÌWÚLÒ ÀTI ÀLÉÉBÙ ÈDÈ ÌPÈ ÀTI ÀTẸ̀JÍṢẸ́ LÓRÍ FÓÒNÙ ALÁGBÈÉKA

**TÁYÉ FATIMA SHEU**

**Department of Nigerian Languages,**

**Kwara State College of Arabic and Islamic Legal Studies,**

**Ìlọrin, Kwara State**

## Àṣamọ̀

*Nínú àpilẹ̀kọ yìí a ó mẹ́nuba ohun tí èdè jẹ́, gẹ́gẹ́ bí ohun tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni jáde fún aráyé gbọ́. A tún gbìyànjú láti sọ ní ṣókí lórí bí fóònù alágbèéká ṣe di lílò ní ilẹ̀ Nàìjíríà. Bákan náà á wo bí a ṣe ń lo èdè nínú àtẹ̀jíṣẹ́, ìjọra àti ìyàtọ̀ ìlò èdè lórí fóònù. A tẹ̀síwájú láti wo ìwúlò àti àléébù fóònù alágbèéká. Lákòótán, a kò ní saláì mẹ́nuba ọjọ́ iwájú fóònù alágbèéká yìí, tí a ó sì kádìí rẹ̀ nílẹ̀ pẹ̀lú ìmọ̀ràn.*

## Kín-ni Èdè jẹ́

Àwọn onímọ̀ ti ṣe atótónu lórí oríkì tí a lè fún èdè. Àbáḷọbábọ̀ ìwòye náà ni pé irinṣẹ́ tó jẹ́ kọ̀ṣéémánìí tí a fi ń gbé èrò ọkàn wa jáde sétígbọ̀ọ́ ẹ̀dá ènìyàn ni èdè jẹ́ (Adéníyì àti Ọ̀nàdípẹ̀, 2002) ohun èlò tí àwùjọ kọ̀ọ̀kan fi ń ní ìbáṣepọ̀ tó gúnmọ́ pẹ̀lú ara wọn ni èdè. Èdè jẹ́ okùn ẹ̀mí àwùjọ. "Awo àjọmọ̀ láàárin èèyàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ láwùjọ asùwàdà ni èdè jẹ́ (Médùbí, 2000).

Adébáyọ̀ (1985) ki èdè báyìí pé:

> Ọ̀nà tàbí ìlànà kan tí àwọn ènìyàn ń gbà láti máa tẹ̀lé fi ronú, kẹ́dùn, yọ̀ tàbí ṣe àwọn mìíràn yálà nípa ọ̀rọ̀ sísọ tàbí ìwé kíkà lọ́nà tí ó fi le yé ẹni tí ó ba mọ ìlànà rẹ̀.

Bákan náà ní Fájẹ́nyọ̀ (2005) fún èdè ní oriki báyìí pé:

> Èdè ni ọ̀nà tí à ń gbà fi èrò wa hàn sí ayé gbọ́, òun náà sì ni ìró tí a sọ jáde láti ẹnu tàbí tí a kọ ṣílẹ̀ tí a fi èrò ọkàn wa hàn tí ó sì ní ìtumọ̀ ẹni tí ó ń gbọ́ ọ tàbí kà á.

Nínú gbogbo ìtumọ̀ yìí, a rí i wí pé èdè ni a fi ń ṣọ̀rọ̀, òun ni a fi ń tajà, òun ni à ń lò láti fi ṣiṣẹ́. Láìsí èdè kò lè sí ìbàṣepọ̀ tó dán mọ́rán láàrin ọmọnìyàn lórí pé òun ló jẹ́ àmì ìyàtọ̀ tó wà lááárin ènìyàn àti ẹranko. Ojoojúmọ́ ni à ń sọ èdè jáde lẹ́nu, gbogbo ẹ̀yà tó wù kí ènìyàn lè jẹ́ yálà Íbò, Haúsá, Nupé, Ijaw, Itsekiri, gbogbo wọn èdè ni wọ́n fi ń ṣọ̀rọ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èdè tí wọ́n ń sọ náà yàtọ̀ sí ara wọn, ènìyàn ní láti kọ́ èdè mìíràn yàtọ̀ sí èdè abínibí rẹ̀ kó tó lè gbọ́ ọ ni. Nítorí náà, èdè wúlò púpọ̀ ní àwùjọ adáríhunrun.

## ÌPÈDÈ LÓRÍ FÓÒNÙ ALÁGBÈÉKA ÀTI ÀTẸ̀JÍṢẸ́

Ní ọdún (2003) ni Ààrẹ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà nígbà náà, Ààrẹ Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ gbé ẹ̀rọ alágbèéka yìí jáde fún àwọn ọmọ Nàìjíríà láti lè máa pe ara wọn láì kúrò nínú ilé wọn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé fóònù alágbèéka ti wà ní ìlú òyìnbó ti

pẹ́, fóònù orí tábìlì nìkan ló wà ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà tó sì jẹ́ wí pé ilé àwọn olówó àti ilé-iṣẹ́ ńláńlá nìkan ni a ti lè rí i, ṣùgbọ́n báyìí àti olówó àti tálákà, ọmọdé àti àgbà, gbogbo ènìyàn ló ń lo fóònù alágbèéka.

Tí a ba wo ọ̀rọ̀ sísọ lórí fóònù, a rí i wí pé kò kún tó, bí a ṣe lè bára wa ṣọ̀rọ̀ ní ojúkojú, kò le dàbí ti orí fóònù. Ìdí èyí ni wí pé bí ènìyàn ba ṣe rí owó ra kírẹ́dîìtì (credit) sí ni yóò ṣe ṣọ̀rọ̀ sí. Bákan náà àwọn fóònù alágbèéka kan wà tó jẹ́ wí pé bí ènìyàn ba ti ṣọ̀rọ̀ ju ìṣẹ́jú márùn-ún lọ, fóònù a máa góná ni. Ìgbà mìíràn tilẹ̀ wà tó jẹ́ wí pé tí ènìyàn ba pẹ́ kò ní wọlé sí ọ̀dọ̀ ẹni tí a pè ní àkókò tí à ń pè. Tí kò ba sì ti wọlé, ọ̀nà mìíràn tí á gbé e gbà ni ká tẹ àtẹ̀jíṣẹ́ ìwé ránṣẹ́ láti orí fóònù láti lè fún ẹni náà ní àǹfààní láti mọ̀ wí pé à ń ba òun ṣọ̀rọ̀, ṣùgbọ́n gbogbo ohun tí a ba kọ jáde lórí fóònù kì í kún tó.

## ÌLÒ ÈDÈ GẸ̀Ẹ́SÌ ÀTI YORÙBÁ NÍNÚ ÀTẸ̀Ẹ́JÍṢẸ́

Ẹ jẹ́ kí á ka àtẹ̀jíṣẹ́ yìí:

> Ẹ má gbàgbé láti gba iṣẹ́ yín lọ́wọ́ Àlùfáà tí ẹ ní kí á
> gbé e fún. A ti parí rẹ̀. Ó dìgbà kan náà.

Tí a ba ka lẹ́tà yìí, a rí i wí pé kò kún tó, kò ṣe àlàyé irú iṣẹ́ tí wọ́n fi ránṣẹ́.

Lẹ́tà Keji:

> Sàlámúàlékún ìyawa

Ẹ kú ọjọ́ mẹ́ta

Ẹkuitọju wa

Oluwayobansalekun dadafunyin

Ikonisidaynida rayni Olaiyianabi.

Tí a ba ka lẹ́tà keji yìí, a rí i wí pé ẹni tó kọ lẹ́tà Yorùbá yìí, kò mọ Yorùbá kọ dáradára, ọgbọ́n orí àti òye ni ènìyàn fi le kàá kó sì túmọ̀ ohun tí ó ṣọ̀rọ̀ lé lórí.

Lẹ́tà mìíràn tún ni:

Ẹkú ìrọ̀lẹ́ Alhaja

Ọlọ́run yo rànyín lọ́wọ́ àmín.

Lẹ́tà yìí kò kún tó, kò sí àlàyé lórí rẹ̀ ju ìkíni àti àdúrà lọ.

Nínú ìlò èdè Gẹ̀ẹ́sì àtẹ̀jíṣẹ́ orí fóònù, wọ́n máa ń ṣe àgékúrú ìró nígbà tí wọ́n bá ń kọ lẹ́tà ránṣẹ́, bí àpẹẹrẹ:

> Thank u so much, I'm grateful indeed. May d Lord b there 4 u at every point for ur need 2day 2morrow the nd always àmín.

Bákan náà ni àmúlùmálà èdè àyálò (Gẹ̀ẹ́sì) máa ń wà nínú ọ̀pọ̀ ìfìwéránṣẹ́ tí àwọn ènìyàn máa ń ṣe.

Ṣe ẹni idea ìgbà tí school má a resume?

Èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Yorùbá ni ẹni tí ó kọ ìwé yìí ránṣẹ́ lò. Tí a bá ka gbogbo àwọn lẹ́tà orí fóònù, a rí i wí pé èdè tí àwọn ènìyàn gbọ́ tí wọ́n sì le kà ni wọ́n fi kọ ọ́ síta. Ṣùgbọ́n àwọn lẹ́tà náà kò kún rárá, ohun tí ó fa èyí ni wí pé, ẹlòmíràn kò mọ̀-ọ́n-kọ rárá, fóònù ẹlòmíràn kò lè gba lẹ́tà púpọ̀, ìfìwéránṣẹ́ orí fóònù kò fi ààyè ṣílẹ̀ fún àlàyé púpọ̀. Yàtọ̀ sí àwọn wọ̀nyí, ìgékúrú ọ̀rọ̀ bí i yíyọ ìró kúrò nínú ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì máa ń wáyé síbẹ̀síbẹ̀ sàsà ni ọ̀rọ̀ tí a lè kọ sórí fóònù tó lè kún ojú òṣùwọ̀n.

## ÌJỌRA ÌLÒ ÈDÈ NÍNÚ ÌPÈ ÀTI ÌFÌWÉRÁNṢẸ́ LÓRÍ FÓÒNÙ ALÁGBÈÉKA

1. Èdè tó jẹ́ èdè abínibí ẹni àti èdè Gẹ̀ẹ́sì ni a máa fi ń bá ara wa ṣọ̀rọ̀ tàbí kọ lẹ́tà ránṣẹ́, èyí tí ẹni tí à ń bá ṣọ̀rọ̀ bá fẹ́ ló lè lò, níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ wí pé èdè ni méjèèjì tí ènìyàn sì gbọ́ ọ tí ó sì le kàá dáradára.
2. Èdè méjèèjì ni a fi ń bá ara wa ṣọ̀rọ̀ tí ẹni tí à ń sọ ọ́ sí yóò sì máa dáhùn kíákíá bí ẹni wí pé a jọ dúró ni.
3. Èdè kan náà ni a máa fi ń dáhùn nígbà tí wọ́n bá pe fóònù wa, bí àpẹẹrẹ: Hello, haloo.

## ÌYÀTỌ̀ ÌLÒ ÈDÈ NÍNÚ ÌPÈ TÍ ÌFÌWÉRÁNṢẸ́ LÓRÍ FÓÒNÙ ALÁGBÈÉKA

1. Èdè Gẹ̀ẹ́sì fi ààyè ṣílẹ̀ fún ìyọkúrò ìró nígbà tí wọ́n bá ń kọ lẹ́tà lórí fóònù, bí àpẹẹrẹ:

Your – ur

This – dis

With – wt

You – u

From – 4rm

For – 4

When – wen

See – ce

Love – lv

A kò lè yọ ìró kan kúrò nínú ọ̀rọ̀, nígbà tí a bá ń kọ lẹ́tà lórí fóònù.

2. Èdè Gẹ̀ẹ́sì ni ọ̀pọ̀ ènìyàn máa ń lò láti fi fìwéránṣẹ́ sí ara wọn. Ìfìwéránṣẹ́ orí fóònù ní èdè Yorùbá kò yá á kà fún àwọn ènìyàn bí i ti èdè Gẹ̀ẹ́sì.

## ÌWÚLÒ ÌLÒ ÈDÈ LÓRÍ FÓÒNÙ

Kò sí ohun tí Olódùmarè dá sílé ayé tó dára tí kò sì tún ní ìwúlò àti àléébù tirẹ̀, fóònù alágbèéka yìí wúlò púpọ̀ ní àwọn ọ̀nà wọ̀nyí:

1. Ó jẹ́ kí ọ̀nà ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ láti ìlú kan sí èkejì yá láàrin ìṣẹ́jú kan. Tí a bá ń bá ara wa ṣọ̀rọ̀ lórí fóònù ó máa ń dàbí ẹni wí pé a dúró ti ara wa ni.
2. Bí arúfin bá sá mọ́ ọlọ́pàá lọ́wọ́, wọ́n lè fóònù ọ̀nà ibi tó lọ kí wọ́n sì mú un.
3. Fóònù alágbèéka ní lílò dín ewu ìrìnnà kù, bí àpẹẹrẹ: ibi tí ó yẹ kí ènìyàn lọ, kó wọ mọ́tò, nígbà tí fóònù ti di kárí ayé, ìrìn àjò ti dínkù.
4. Ó mú kí ọkàn ẹni máa fà sí ara ẹni bí ololufe, ẹbí àti ọ̀rẹ́ níwọ̀n ìgbà tí nọ́ḿbà bá ti wà ní ọwọ́ ènìyàn kíá ni ènìyàn yóò tẹ̀ ẹ́ tí á sì wọlé.
5. Ìròyìn ohun tó bá ṣẹlẹ̀ tètè máa ń kan ènìyàn.
6. Ó mú ọ̀nà ìsòwò rọrùn fún ẹni tí ó ń tà tí ẹni tí ó ń rà, bí àpẹẹrẹ; bí ènìyàn bá fẹ́ máa ìyá ọjọ́ kan tí ènìyàn bá ti pe oníbàárà eeyan kíá ni yóò sọ iye tó jẹ́.

Fóònù alágbèéka jẹ́ ohun tí a lè fi ọ̀rọ̀ pamọ́ sí inú rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iranti, bákan náà tí ènìyàn bá fẹ́ ṣe nǹkan ní déédé àsìkò kan, tí ènìyàn bá ti tẹ̀ ẹ́ sí àkókò náà. Tó bá ti tó àsìkò yóò han láti rán ènìyàn létí ohun tí ó fẹ́ ṣe.

## ÀLÉÉBÙ FÓÒNÙ ALÁGBÈÉKA

1. Á mú kí ìyapa wà nínú ẹbí, torí ẹni tí a gbóhùn rẹ̀ lórí fóònù a ò ní saáyan àti wá a lọ.
2. Lẹ́tà kíkọ yóò dàkọ̀tì, nígbà tí a bá ti gbúròó eeyan lórí fóònù a ò ní fẹ́ kọ lẹ́tà sí i mọ́.
3. Àtẹ̀jíṣẹ́ orí fóònù, ó jẹ́ kí àkọtọ́ mẹ́hẹ nítorí ìgbìyànjú àti ṣe igekuro kí owó lè mọ níwọ̀n ní.
4. Ó jẹ́ kí àwọn ọ̀dọ́mọdékùnrin máa gbé àwòrán tí kò dára sí ojú fóònù wọn.
5. Orin gbígbọ́ lórí fóònù tí wọ́n ń ti wáyà bọ etí ní ojú títì kò jẹ́ kí opolopo gbọ́ nígbà tí mọ́tò bá ń fọn yàgò lójú u títì.
6. Ó mú kí àwọn ènìyàn máa parọ́ ibi tí wọn kò wà nígbà tí wọ́n bá ń pè wọ́n.
7. Pẹ̀lú ìwé ìpè tó wà nínú ọ̀pọ̀ fóònù kò jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa lọ sí yàrá ìkàwé dáadáa (library).
8. A má ń fi fóònù kan ènìyàn ní àbùkù, bí àpẹẹrẹ; tí èèyàn kan bá pè, tí ènìyàn bá ti rí nọ́ḿbà, èèyàn kò ní gbé e, tí ènìyàn bá sì gbé e èèyàn lè sọ wí pé "máa pè ẹ́ pada". "O busy", "mo hún jẹun lọ́wọ́" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
9. Ó mú kí àwọn ọ̀dọ́ dágbálé ohun tó jù wọ́n lọ nípa lílo fóònù olówó ńlá-ńlá.

**Ọ̀JỌ́ IWÁJÚ FÓÒNÙ ALÁGBÈÉKA**

Tí a bá wo bí fóònù náà ṣe wúlò fún ènìyàn báyìí, ó ti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ̀pọ̀ ènìyàn, bẹ́ẹ̀ náà ló sì ṣe aburu fún ọ̀pọ̀ onímọ́tò èrò, ibi tí a lọ pẹ̀lú àpò méjì àbọ̀ nígbà tí ènìyàn bá fi máa ná igba náírà yóò sọ ohun tó fẹ́ sọ. Fóònù alágbèéka yóò mú kí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn máa ṣe ọ̀lẹ sí ohun tó yẹ kí wọ́n ṣe, wọn kò ní já gìrì. A tún mú kí olè jíjà pọ̀ si ní àwùjọ wa, torí tí ènìyàn bá ń pe nọ́ḿbà kan tí ènìyàn bá ń pe nọ́ḿbà náà sókè, wọ́n lè ti ibẹ̀ mú nọ́ḿbà kí wọ́n sì tún pè é kí wọ́n mọ ilé tàbí ibi iṣẹ́ ẹni náà láti lọ ṣe é lọ́ṣẹ́

Nígbà tí ó bá yá fóònù kò ní pada wúlò mọ́ torí tọmọdé tàgbà, arúgbó jọ̀kú-jọ̀kú, torí oko ni yóò máa lo, ọjà fóònù náà ní títà kò ní yá mọ́ lọ́dọ̀ àwọn tí wọ́n fi ń ṣiṣẹ́ ṣe.

## ÀGBÁLỌGBÁBỌ̀

Nínú àpilẹ̀kọ yìí, a ti wo bí a ṣe ń lo èdè nígbà tí a bá ń pè tàbí nígbà tí a bá ń fi àtẹ̀jíṣẹ́ ránṣẹ́ lórí fóònù, ìyàtọ̀ àti ìjọra tó wà nínú ìpè Gẹ̀ẹ́sì àti ti Yorùbá, ìwúlò àti àléébù fóònù lawujo, ọjọ́ iwájú fóònù alágbèéka, ṣé yóò máa tẹ̀ síwájú ní lílò ni tàbí a kọ̀ ọ́ ṣílẹ̀ ní lílò. Torí náà tí a bá ń lo fóònù alágbèéka wa kí á wo ọ̀tún àti òsì, kí á mọ ohun tí á bá sọ jáde nítorí àwọn ọlọ́sà tàbí aláburú ẹ̀dá, kí á ṣe àmúlò èdè dáadáa nígbà tí a bá ń pè tàbí tí à ń pè tàbí tí a bá ń fi ìwé ránṣẹ́ lórí fóònù alágbèéka wa.

# ÌWÉ TÍ A LÒ

Adébáyọ̀, A. (1985). *Èdè àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: Macmillan Nigeria Publishers Ltd.

Adéníyì àti Ọnàdípẹ̀, T. (2002). "Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Yorùbá", nínú Adéníyì, Harrizon (Olóòtú). Ìlò èdè àti ẹ̀dá èdè Yorùbá, Apá kìíní. Lagos: Harade & Associates.

Fájẹ́nyọ̀, O. (2005). *Yorùbá Gbòde*, Fol. 4, No.4, 2010, Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà.

Médùbí, D. (2000). "Àmúlò èdè Yorùbá" nínú Adéníyì, Harrison (olóòtú). Ìlò èdè àti ẹ̀dá èdè Yorùbá. Apá kìíní. Lagos: Harade & Associates.